AJ'OMOGBE BE S'ODO O B'ODO LO



SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO


LAGOS

VOL. No. VIII 495. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, NOVEMBER 24, 1956. KOBO MEJI (2d.)

# Ajomogbe Be S'odo O Ba Odo Lo

Ọkunrin Igbira kan ni a gbọ wipe o ri ọmọde kan nibiti ọmọ na gbe nṣere, o sunmọ o si fun ni akara nigbati ọmọ na jẹ akara tan, o paṣẹ fun ọmọ na pe ki o tele on, laimọ pe baba ti o bi ọmọ na nwo on l'okere. Gbogbo iṣesi re ni baba ọmọ na ti nṣọ, ọmọ na si tele.

Nigbati awọn de ebute Irọ, ni Igbira ba gbe ọmọ na sinu ọkọ lati wa lọ. Baba ọmọ ti o nṣọra tele wọn wa bere lọwọ ọmọ re wipe nibo ni ọmọde na nlọ? ọmọ na ko le sọrọ, o nọka si Igbira.

Bi baba ọmọ ti fẹ bere lọwọ Igbira pe, ewo l'ode o, beni o ra lu'mi, baba ọmọ si tọ ọ. Igbira na mọwe pupọ bi o ti nwe lọ beni Ọni kan ri, o si gbee, o wa bere si k'igbe, e gba mi, e gba mi.

Gbogbo enia lo dide lati lọ gba sile, ṣugbọn ki nwọn to we de ibẹ Ọni ti teri sinu omi.

Beni aj'ọmọgbe ba odo lọ ti nwọn ko ri mọ.

Ṣugbọn awọn ara ilu Irọ ti ko mọ bi ọrọ na ti jẹ, wa lọ gbe ọkọ s'oju omi pẹlu ibọn lati wa Ọni ti o gbe odidi enia lọ.

Baba ọmọ na pe wọn jọ o wipe e kure nidi aapọn ti ko ni yọ. Aji-ọmọ-gbe ni, Ọlọrun lo si dajọ fun, o si rohin fun wọn bi gbogbo ọrọ na ti lọ.


## THE NATIONAL BANK

### Of Nigeria Limited

Be ifi Owo pamọsi yi.
Nfi ọna owo han enia
Bi o ba fẹ jẹ oniṣowo pataki ae
tan ọ lọwọ aipa wipe ao tọ ọ
si Ọna to dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti a nta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina, Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU OYINBO :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.

The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


# Gomina Ijoba-Ila-orun fise sile



Sir Clement John Pleass ti o nṣe Gomina fun ijọba Ila--Orun, ẹniti a gbọ wipe o gba isimi oṣu meji lo si ilu Oyinbo, lo ti fi iṣe ijọba Ila-orun sile.

A si tun gbọ wipe Alaiyeluwa ọba obinrin ilu Oyinbo, ti gba iwe ifiṣe silẹ rẹ.

Ẹniti ọba oyinbo yan lati wa dipo re ni Ọgbẹni Robert de S. Stapledon ti o nṣe Sẹkiteri agba nilu Tanganyika, ijọba Gẹsi si ti fun Ọgbẹni yi loye K.C.M.G. ki o ba le to ẹniti o to ipo na mu dani.

Nigbati awọn ara ile Ibo gbọ wipe Gomina yi ti fi iṣẹ silẹ, inu wọn dun, nitoripe nwọn ko fẹ lati ba se pọ mọ nigbati ede aiyede ti bẹ silẹ larin on pẹlu awọn igbimọ ijọba Ila-Orun

# Israeli fe k'ogun pari

Ọgbẹni David Ben Gurion ti nṣe Prime Minister fun ilu Israel ni o sọ fun awọn Rọsia wipe ki nwọn pari ija ti o mbẹ larin awọn ara ilẹ Egypt ati awọn ọmọ Israel.

Iwe Irohin Amẹrika kan sọ wipe o ni lati jẹ wipe Gẹsi, Faranse ati Israeli ti mulẹ pupọ ki nwọn to gbo ju-gbaiya ṣagun si Egypt.

Ni ọsẹ tokọja ni a gbọ wipe Rọsia ranṣẹ si Israeli wipe awọn nilati san'wo dukia ti Egypt padanu ninu ogun na ṣugbọn Israeli laku wipe iyẹn ko le ṣe, ati pe on ko ba ẹnikan mulẹ l'ori Egypt.

Iye awọn enia ti Israeli padanu lati ọwọ awọn Larubawa ti o mbẹ l'agbegbe wọn jẹ ẹdẹgbẹta lo-lẹgbẹa enia.

## Nwon Be Omode Lori

Ọmọde'kunrin kan, ọmọ ọdun marun ni a gbọ wipe awọn bẹ lori sinu igbo ni abule Ahoyaya l'ẹba Ikire

Awọn obi ọmọ na sọ pe ere ni ọmọde na sọ wipe on lọ se ti awọn ko fi ri abọ rẹ mọ. Ọrọna mbẹ lọwọ awọn ọlọpa.


TO CLEAR

Obtainable at:-
A. B. AKINYEMI
LAGOS.

## Irora Ni Orikerike Ati Isan Ara

BOYA ARUN IGBAROKO LOFA



Ise ti KIDINRIN ͅsͅe ni ... ni pe ki nwon ... fi gbogbo idoti ti o wa ninu ara danu. Bi awọn Kindinrin awọnyi ko ba sise deradara awọn idoti ara na yio ma ... si ... fa ... fun ... si orikerike ... ara.

Ọna ti a le gba ti ... gbogbo arun yi ... ki a ... fun Kidinrin ... ti a ... ni DE WITTS ... se na.

Nitori ... arun ... ti a ... gbogbo ... ti ... ninu ... Kidinrin ...

A ... gbogbo DE WITTS yi ... Kakiri gbogbo agbaye ... [illegible]

... ọdọ ọ dẹrọ li iwọ ko danwo fun ara rẹ ... lọ ... ọ ... wo.

... DE WITTS dara fun ... Orike, Lakuregbe ... arun ... ati.

... o ... DE WITTS ... gbogbo ... [illegible]



**DE WITT'S PILLS**

**for Kidney and Bladder Troubles**


---

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Fun Irohin Aladun Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re

---

## Oloye S. L. Akintola



Ẹnu a nwo yi ni Oloye S.L. Akintola, ... lo pe ipade gbogbo awọn Minister wipe, ki nwọn wa, ki nwọn rọ ... sọ asọyẹ pọ nipa owo bi Ọkẹ mẹdogun Poun £300,000 ti nwọn nfẹ na lati fi kọ ile fun awọn Minister laifi ba ẹnikan sọ.

Boya ile ẹlẹgbaa mẹfa ti ijọba fi kọle si Ikoyi fun awọn Minister ko to ẹnikọkan wọn ni, o si yẹ ki a mọ kini awọn nfẹ kọ ile yi fun, tori kini, anfani wo lo si wa nibẹ ?

Gbogbo nkan anfani ti nwọn nilati fi owo ṣe, awọn igbimọ Minisita ko risi iwọnyọn afi ile Ọla, bi afin ile ọba ni nwọn nfe l'ati ma gbe

---

## TALAKA PARAPỌ NYỌ FUN IṢẸGUN

ILỌRIN — Awọn Ilọrin Talaka Parapọ yọ ayọ iṣẹgun wọn lori N.P.C. ni Ilọrin ati ni Offa laipẹ yi.

Gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ yi lọ jade nimu ayọ to jire ti nwọn si njo, ti nwọn si nyọ. Nwọn lọ sile ọba Saki, ọba Ilọrin, awọn lọ ki ọba na, awọn dupẹ fun nitori ti ko da rukerudo silẹ nigbogbo asiko igba ti nwọn ndibo.

Alhadji Abdul Kadiri fi tayọ-tayọ gba wọn lalejo, o ta wọn lore, nwọn si tuka.

---

No. 168.

## KING'S COLLEGE LAGOS

### ENTRANCE AND SCHOLARSHIP EXAMINATION 1957.

The Entrance and Scholarship Examination for admission to King's College, in January, 1958, will be held on Saturday, March 30, 1957.

2. Candidates wishing to enter for this examination will received application forms particulars of scholarships and conditions of entry by carrying out the following instructions:

(I) Put your name and full postal address in BLOCK LETTERS on an empty, open foolscap envelope (a foolscap envelope measures 9in, by 4in.)

(II) Stick a 2d, postage stamp in the top right-hand corner of this envelope,

(III) Put the stamped, addressed envelope inside another, addressed to:

THE OFFICER-IN-CHARGE OF EXAMINATIONS, KING'S COLLEGE, LAGOS.

and post it to reach him not later than 15th January, 1957. Application forms will not be sent to any candidate who does not carry out the above instructions exactly and no correspondence will be entered into about them. The Officer-in-Charge will not received applications in person and will not interview any intending candidates,

3. The application form will give full instructions on the method of applying for entry to the examination.

4. Requests for form will not be considered after 15th January, 1957, and completed application forms must reach the Officer-in-Charge not later than 15th February, 1957.

5. The examination will be held in Lagos, Bamenda, Buea, Kumba, Mamfe, Aba, Afikpo, Awka, Calabar, Ogoja, Okigwe, Onitsha, Owerri, Port Harcourt, Umuahia, Uyo, Ilorin, Jos, Kano, Lokoja, Makurdi, Minna, Zaria Abeokuta, Akure, Asaba, Benin City, Ibadan, Ijebu-Ode, Ilesha, Ondo, and Warri.

6. Improper attempts to influence members of the College staff regarding the admission of any candidate will result in the disqualification of the candidate on behalf of whom the attempt is made.

---

No. 169.

## The Nigeria Police - Vacancy

Application are invited from suitably qualified persons for enlistment into the Nigeria Police as Woman Police Constables.

2. Candidates selected will be required to pass an Entrance Examination into the Southern Police College, where they will undergo as recruits a six months course of training. On successfully passing out of the Police College, they will be appointed Third Class Woman Constables and be posted for duty.

3. The following qualifications are required of applicants seeking enlistment

| | |
|---|---|
| EDUCATION | Must be literate and must have reached a Standard of Education equivalent to Class II Middle School Certificate. |
| AGE | Shall not be less than 19 years of age or more than 25 years of age. |
| HEIGHT | Shall not be less than five feet four inches, |
| CHARACTER | Must be of good character and not have been convicted of any criminal offence. |

4. Applicants must be unmarried, of good physique and devoid of any physical deformities.

5. Application forms can be obtained from the Senior Superintendent In-charge of the Police Province in which the applicant resides and must be returned to that Officer not later than 10th December, 1956.

# Gesi Koja, Eila L'o Laja

LONDON. Nigbati rogbodiyan ogun fi ṣelẹ ni ilẹ Egypt, eyiti gbogbo aiye fi nlu kẹkẹ wipe ogun o ! ogun ti bẹrẹ nilẹ Egypt larin Gẹsi ati Egypt. Ẹniti ko ba gbọ t i ẹnu eiyẹ Ẹga, yio wipe aṣe ni Ẹga npatoto. Bi ọrọ na ti lọ niyi.

Larubawa meji lo mba ara wọn ja, eyi ni Egypt ati Israẹli, nwọn si ti mbẹ lẹnu ija na ọjọ pẹ. Nigbati o ṣe ni Isreal gbogun si Egypt.

Ijoba Gẹsi ati Faranse ṣe ikilọ fun awọn onija mejeji wipe, ayafi bi nwọn mejeji ba tuka ni kiakia, ki nwọn si rin jina bi ibuso mẹwa si ebute Suez, bi bẹko, Gẹsi ati Faranse yio ko ọmọ ogun rẹ wa lati pari ija.

Israẹli gbọ ikilọ na, o si pada sẹhin, ṣugbọn Egypt taku, o si lepa awọn ọmọ Isreal titi de afonifoji oke Sinai, nibẹ ni nwọn si fi ija pẹ ẹta.

Kiakia ọmọ ogun Gẹsi ati Faranse ti lọ gba ilẹ ni agbegbe ebute Suez, ki ọwọ awọn onija mejeji maṣe le to ara wọn. Ohun ti o jẹki Gẹsi ati Faranse ṣe bẹ ni wipe ogun kekere yi le gberan di nla.

Ohun ti Gẹsi ati Faranse ṣe yi, ko si imọran ti ilu kan nibẹ, bẹni ko si imọ t i Amerika pẹlu. Awọn ẹgbẹ Majẹobajẹ ṣe ipade lori iwa ti Gẹsi ati Faranse hu yi, gbogbo wọn si f'ohun ṣọkan pe a ti huwa ti ko dara, ṣugbọn nigbati o ṣe ti wọn ri pe eyiti aṣe yẹn gan-a lo tọ suna, nwọn yi ohun pada, adehun ti nwọn tun ṣe ni wipe, ki awọn ẹgbẹ Majẹobajẹ yan ọlọpa lati orisiriṣi ilu lọ wa alafia silẹ Egypt.

Idi rẹ ti Gẹsi ati Faranse ṣe huwa bẹ ni wipe awọn ẹgbẹ Majẹobajẹ ko ni le tete pana ija na bi a ba wipe ki a fi ọrọ na le wọn lọwọ. Nigbati o si jẹ pe, ọwọ ẹni la fi ntun iwa ara ẹni ṣe lo jẹki a tete gba ọna to ya.

Eyiti a ṣe yi, a ni mimọ pe ọpọ enia lo ni ikunsinu si awọn Gẹsi kakiri agbaiye papa awọn alatako igbimọ wa lodi si pẹlu. Ṣugbọn ijọba Gẹsi mọ wipe eyiti nwọn ṣe yẹn gan ni ọna ti o ya lati pari ija na.

## Efon pa obinrin kan

BIRNIN GWARI– A gbọ irohin lati Oke Oya wipe obinrin Hausa kan gbe onjẹ lọ fun ọkọ rẹ ninu oko, bi o si ti npada bọ wa sile ni o ṣe agbako pade ako Ẹfọn kan l'oju ọna.

Obinrin na kebosi, ṣugbọn ko si enia nitosi lati ṣe iranlọwọ nitoripe ibẹ jẹ aginju-igbe. Efọn na si pa obinrin na l'ẹfẹ-l'ofo.

Ẹfọn jẹ ẹranko kan ti iri rẹ dabi ti Malu ẹranko, nṣe ni iwo ka mọ l'ori gẹgẹbi iwo ẹran agbo, iba iyatọ rẹ si Malu ni wipe o ni gogo l'ọrun gẹgẹbi Kiniun tabi Ẹṣin.

## *NOTICE TO CREDITORS*

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF MORADEHUN AMOPE DECEASED

Notice is hereby given that all creditors and other person having any claims or demands against the estate of Moradahun Amope late of Oke-Arin Street, Lagos who died testate on the 16th day of Sept 1955 and Probate of whose will was on the 16th day of August 1956 granted by the High Court of Lagos to Murano Ayinde Thompson and Tajudeen Akintọla Thompson the executors named in the said will are required to send in writing particulars of their claims or demands to the undersigned on or before the said excutors shall proceed to administer the estate of the deceased and distribute the assets of the said deceased among the persons entitled thereto having regard only to the claims or demands of which notice shall then have been received.

And all persons indebted to the said estate are required to make immediate payment.

Dated this 30th day of October, 1956.

A. K. I. Makanju
Solicitor to the Estate

MA FI

BLUE BAND




Blue Band dun pupọ lori bread gige, gbogbo enia li o fẹran rẹ! Blue Band nran awọn ọmọ wẹrẹ lọwọ lati dagba, o fun wọn ni ilera o si nran wọn lọwọ lati lagbara fun iṣẹ ṣiṣe. Gbogbo idile ti o ba njẹ Blue Band lojojumọ a ma gbadun rẹ lọpọlọpọ.







BLUE BAND dun,
o si ngeni l'anfani

## IRIN AJO

Enikẹni ti o ba fẹ rin irin ajo, yala lẹnu iṣẹ tabi fun faaji lọ si ibikibi ni apa ilẹ Nigeria, tabi lọ si apa ilẹ Iwọ-Orun Africa tabi lọ si ibikibi ni agbaiye.

WA BERE

Lọdọ awọn AMONA irin ajo, yala lori omi, l'oferufu tabi lori ile ninu ọkọ Reluwe.

Jẹki a ba ọ ṣe gbogbo wahala rẹ nipa Iwe iṣẹ fun irin ajo (Passports) Iwe Ọkọ-ilẹ (Tickets) aye Ijoko ati Idọkanbalẹ jamba (Insurance).

Ajo ba ero Mẹka ṣeto Ọkọ pelu irọrun. Iranṣẹ ni aje fun ọ lo wa.

**West African Travel Agency Co.**

9, Victoria Street, Box 581,
LAGOS PHONE 23237.

# ELETI OFE

[illegible]

"ELETI - OFE LAGOS"

VOL. [illegible]    LAGOS, SATURDAY NOV. 24 1956.


## Innkunna Owo Niyi

[illegible]

[illegible]

[illegible]

[illegible]




## Awon Aje Mbe Fabi Kosi ?

Olotu,

ghọ mi laye lati [illegible] awọn ọkawe [illegible] bi o ba jẹ wipe looto ni awọn Aje wa?

Emi mọ daju wipe awọn ọda kan wa ti nwọn npe ni Aje. Sugbọn awọn Yoruba nsu wa gbagbọ wipe, awọn ti a npe ni aje yi, ara awa enia lo wa.

Ina wa yio dun bi a ba le ri ọkan o le fi yeni, bawo ni enia kan ofi eran ara re [illegible] ni wipe ọda ẹlẹgbẹ on lo wu on ni jije?

Emi ni
Alufa Akeremale

[illegible]

## PUBLIC NOTICE
### Posts & Telegraphs Department Notice.

It is notified for public information that due to variations in the normal fortnightly mail boat sailings, the next despatch of surface mail to and via the United Kingdom will be made on 27th November, 1956.

Correspondence in connection with this mail must be posted in Lagos not later than mid-night, 25th November, 1956.

The following despatch will be via the normal sailing on 4th December, 1956.

J. A. FARRER,
Ag. DIRECTOR,
POSTS AND TELEGRAPHS.

No. 144.

## PUBLIC NOTICE
### Posts And Telegraphs Department Notice
Air mails for Egypt.

As from 1st November, 1956, air mails to Egypt have been forwarded by air, via the United Kingdom, to Benghazi for onward transmission by surface route. The usual time from Benghazi onwards is not known but this emergency routing must inevitably involve a certain margin of delay.

J. A. FARRER,
DIRECTOR,
POSTS AND TELEGRAPHS.



## A Nfe Ki Owo Ori Koko Duro Sibikan

BRUSSELS. Olaye Akin Deko ti o nse asoju fun awon ohun ijile ati ohun ogbin ni agbegbe Iwo-Orun ile Nigeria, nigbati awon egbe Agbe ran lo se Asoju won ninu ipade awon egbe gbogbo agbaiye nilu Brussels, se ayan gidigidi nipa Koko Pipon.

O so fun awon iglimo wa wipe yio je ohun ti o dara bi nwon ba le jeki iye owo ti a nsan lori Koko, Pe, duro si ibi kan.

A gbo wipe awon ara Belgium ti ara mo oro ti Oloye Akin so ati Switzerland ati ilu Germani, nigbon Oyo ati Amerika ko ba oro na je.

Nwon so ninu ipade yi wipe pelu agbara Olorun, nile Nigeria ni awon o gbe se ipade kan l'odun 1957. Opolopo oro ni awon so nipa Koko.

## Koiti Daju Pe Ogun Egypt Pari

EGYPT. Lehin ti awon egbe Majoobaje ti da si oro ile Egypt wipe ki gbogbo awon enia dawo ija duro ti awon si ti se be, a tun gbo wipe, awon ogun ile Egypt tun dano mo awon Gesi ati Faranse lera, sugbon a gbo wipe awon Gesi ko dahun nitori oro na awon egbe Majoobaje.

Oko oforofo ti awon Gesi gbogun ti orilede kekere kan ti o nbe leti ebute Said nibiti awon ara ile Egypt gbe ko awon ohun ogun ati awon ohun ogun pamo si.

Ogagun Gesi kan ti nsoro nile wipe ki awon tuabo fun awon jagunjagun ki won le lo fi ipese lori awon ebute, nitori pe okan ti awon ara ilu ko dara.

A gbo wipe gbogbo awon ile ipaba ni awon ti fere gb'agba. Awon nkan pupo lara iyipada ti won se ti tun.

## OWE YORUBA

1. Oju le mowaju ekun, abanu lo n agbebin oro, gbogbo otolukun ilu oojo, a ko ri eloo abamu se.
2. Afefe le no'origi yeri-yeri, efufu lo ate oni agbon aikoro, aikoro, ibio o wa efufu lele lo adari igbepi nibiti a wa alawa eni lo asan ni lo.
3. Af'ogbon ologbon nugbon ko ma ologbon, a f'eru ekeni se ero lo aje omeru ogbon ologbon ni ko oje-ki a pe agba ni won.
4. O wu Aguala ko mole ro agunu Olorun ni ko ti fun Olorun na ni ko da kanyin-kanyin ko ninla ti enia alapa ni ilu ilu, alapa ni iba ra rara Enia ti iba l'anu s'enia Olorun ola ku ni je ku ni lari.
5. Nisi nawon l'ojo, ara ma oko, oko naju korokoro, be Nisi ko je gbe aro re nile fun o.
6. Ekolo nmu igbagu ma nibi adie puru alaba ko nani a okan igbe, lo ma oko ti aje, lesi oloc oko nlo lo.
7. E yo'ka se oke fo apani, gedu-gedu gbomu-gbomu, enili o ba wo k'o be.
8. A arin aile lan mbi ole-jile oke ko le ki a ro oro ka so, ori ani lo nan ni.
9. Ariwo pa-a lekkowa ola fun aroko to bi gbajumo.
10. Oro ba ologbon di aenu go (bi oro baba ologbon yio nada di awugo!

## Ofin Ibeji Mule Ni Ila-Orun

Iroyin kan wa wipe awon ijoimo ilule ilu Eda ni agbegbe ile Afikpo nile awon Ibo, se ipade lori ofin ti iloba ile Ibo se wipe o ikeji ko gbodo ya omo ibeji ati iya won si ipese mo.

A gbo wipe awon iya ibeji ni agbegbe enia ti won ti le lo'gbe aira ni ile'ko kan ti awon ope ni abule Oro (Twin Village) ni Eda ota lehin odi ilu ni awon da pada wa si arin ilu won.

Nibi ipade awon ti nse ati awon ... ilu ti ... ti awon ilu ni marun tun ran enia wa ni nwon ti se ipinnu na. Nwon si tun lohimo ti yio ... l'ati didapada wa si ilu ... ibeji pelu ... Ipade na f'ohun ... wipe ... ti o ba ko ... ibeji ki gbe ba ... n'ejo.

Siwaju eyi, Alufa Alfred Anicho ti ijo Sosi Presbyterian ilu Eda ti sha lati se iwadi awon omo ibeji ati iya won o si ti fimi pada wipe awon mimo owo ti awon ope awon omo ibeji ati iya won o si ti fimi pada wipe awon

nitori ... ti ... ... ... omo ... ... ... Ile Ibo ... ... gbe ...

## Owe Yoruba

Ika ko le kara

eru k'a so, ori eni

l'o so'ni.



## JESU L'ESE TABI KO L'ESE?

Lọjọ Sunday ti o kọja lọ yi ni Alfa Akeremado jiyan pẹlu ọkunrin Aladura kan. Ohun ti o da ọrọ na silẹ niyi:—

Mo fẹ ki ndabi Jesu
Ninu iwa pẹlẹ
Ko si ẹnit'o gb'ọrọ 'binu
Lẹnu rẹ l'ẹkan ri.

Hanin, kinla! ki lo·i yen, tunsọ ki ngbọ? Mo ni ko s'ẹnit'o gbọrọ 'binu lẹnu rẹ lẹkan ri.

Alufa Akeremado sọ wipe kini o gbojule ki o to sọ pe, Jesu ko binu ri tabi ko sọrọ ibinu ri. Aladura na sọ wipe lati gba ti a ti bi Jesu, ko dẹṣẹ ri bẹni ko binu ri. Lẹmọmu si dahun wipe, ngo ṣe alaye fun ọ pe ko si Anọbi ti ko da ẹṣẹ.

1. Nigbati Jesu wọ Tẹmple, ti o ba awọn ti o nta, ti o si nra, ẹṣe ti Jesu ko fi ni suru ki o ba wọn sọrọ Ọlọrun, nọya ao ri ẹyiti yio yi pada ti yio si ... ẹṣẹ rẹ ṣu-... Jesu ko ṣe ..., nṣe ... ti o si ko K.B.K b wọn, e binu tabi ko binu?

2. Nigbati iya Jesu sọ fun pe, ọmọ mi, ọkọ iyawo ko ni oti mọ, kaka ko ba iya rẹ sọrọ ni itunbi-inubi, nṣe lo jagbe mọ iya rẹ bayi pe, fi mi silẹ, obinrin yi, akoko mi ko i ti to. O ṣe si ofin kẹrun.

3. Akoko ẹrun ni gbogbo igi nso eso, ni akoko ojo ni igi aruwe. Nigbati Jesu de idi ọpọtọ, ti o ruwe daradara ti ko si leso lori lasiko ojo Jesu ko le ṣe suru ki o wadi wo ṣugbọn o ṣẹ akọ epe fun igi na. Iru iwa yi kini a le pe wọn, Jesu lẹṣẹ tabi ko ni?

## Awon Onibara Nwonyi Poju

ZARIA— Aṣa awọn Yoruba mọnin-mọnin, nwọn ... pe, nigbati aye gba ... ogunmọ tan, l'o nnni ... odu.

... Zaria a gbọ wipe ... fi aye gba awọn ... Onibara tobẹgẹ ... fi ni ọba, Balogun ati Giwa.

Ati pẹlu-pẹlu, ẹniti ko ba ti ri iṣẹ ṣe yio lọ lẹ ori-amọ mọ oju, yio si gbe igba bara.

Orişirişi ni awọn onibara na, isọwọ Atiro ọtọ, isọwọ arọ, isọwọ afọju, aditi, isọwọ afin ati isọwọ onibori.

Nwọn ko nsanwo ori, bẹni ẹniti o nsanwo ori ko ri ọna rin. Zaria Town Council wa ṣe igbimọ, nwọn sọ bi nwọn o ti ṣe awọn onibara na si si, nitoripe nwọn ti pọju. Mọto ko gbọdọ sare ju, kẹkẹ ko gbọdọ rin. Nwọn ti pọju.

## Lawani wiwe je pataki fun Esin

Lati Ọwọ SAULA BALOGUN

Ọpọ awọn enia lo sọ pe, bi a ba nwe Lawani, nṣe ni a nkọ aṣa awọn Hausa. Rara! eyi ko ri bẹ, rṣe ni awọn Hausa papa nkọ aṣa Larubawa.

Ninu iwe Sakaria 3.3-5. Ọlọrun sọ fun wipe, mọ mu aiṣedede rẹ kuro lọdọ rẹ Emi o si fi aṣọ ẹyẹ wọ ọ. Mo si wipe, jẹki nwọn fi lawani mimọ wé e lori, nwọn si fi aṣọ wọ ọ, angeli Oluwa si duro ti i. Ezikieli 24. 23-24. O wipe lawani nyin yio si wa lori nyin.

Nibikibi ti ẹ ba ri aworan Jesu ti o wọ ẹwu agbada, lawani ni ẹ o tun ri lori rẹ, ati lori awọn ọmọ ẹhin rẹ pẹlu.


### Kere o!

A ti ni orişirişi ogun Germany to ṣeşẹ de, fun onirun aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos



### IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma nba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE
(SILE MEJI ABO 2/6d FUN GO KAN)
O wa Lodọ:—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS





FUN

Agbara Eje ati

Agbara Okunrin

HOMMEL'S

HÆMATOGEN

Hommels Haematogen jẹ egbogi ti a ṣe ninu ẹjẹ akọ Malu, yio fi ẹjẹ rere tun ara rẹ ṣe, ati irin ti yio fun enia lagbara bi akọ Malu.

O mbẹ ninu igo fun tita yika Ṣọbu ilẹ Nigeria.

Fun Agbara iṣẹ l'ọsan,
Fun ilera lẹhin iṣẹ ati ere şişe.



Rere Lodo Asoju wa—
ALBAN PHARMACY LIMITED,
2, Victoria Street, P. O. Box 461.
Lagos – Nigeria.

No.73/S.2/VOL.VII/301

## Ministry of Education, Western Region

### GOVERNMENT TRADE TRAINING CENTRE, SAPELE

1. An entrance examination for admission to the Government Trade Training Centre, Sapele will be held on 9th February 1957.

2. Trainees will be selected from this examination for full-time residential courses for Electricians (3 years) and a number of other Trades.

3. The entrance examination will consist of written papers in English and Arithmetic; there will also be tests in general knowledge and sketching. There will be examination centres at Akure, Agbor and Sapele.

4. To be elegible to sit for the examination, all of the following conditions must be complied with:-

(a) Boys must not be more than 17 years of age and not less than 15 years of age on 1st March 1957.

(b) They must have been born in or attended school in the Western Region or be of Western parentage.

(c) They must possess a Primary VI School Leaving certificate.

5. Application forms to sit the examination must be obtained from the Principal, Government Trade Centre, Sapele. The completed forms must be returned to the Principal to reach him not later than 5th January 1957. Each application form must be accompanied by:-

(a) An examination fee of 2/6, in the form of a Treasury Receipt (Postal Orders, Money Orders or cash will not be accepted for the examination fee).

(b) A photograph (2" x 2") of the applicant's head and shoulders.

Forms which are received without the Treasury receipt, or which arrive after 5th January 1957 will not be accepted. The examination fee is not returnable.

6. Applicants who comply with the above conditions will be notified by the Principal, and informed of the time and place to attend for the examination.

7. Candidedates who attend for the examination are required to bring with them:-

(a) A Birth certificate or sworn declaration of age. (A Baptismal certificate is invalid for this purpose)

(b) Their Primary VI School Leaving certificate.

Candidates who are unable to submit evidence of the required age and educational qualifications are warned that they will not be admitted to the examination.

Candidates who are successful in the examination will be notified when and where they will be required to attend for personal interviews, but such candidates should note that final selection for admission to the Trade Centre will not be made untill after interviews have taken place.

Fees are £15 per annum and are payable in advance ...er.

It is likely that the number of suitable candidates will ... the number of vacancies available and while consider... will be given to the preference of the selected candidates, it should be clearly understood that they must be prepared to accept whatever trade course may be offered.

General conditions for admission and regulations can ...ed from the Principal, but no reply will be sent to letters addressed to the Principal on the subject of the acceptance or rejection of any candidate.

## Ogbeni Anthony Eden



Ẹniti a nwo yi ni Ọgbẹni Anthony Eden ẹniti o nṣe Prime Minister nilu Oyinbo, on lẹniti o fi jagudu pali pari Ija ogun larin ilu Egypt ati Israeli

Awọn Amerika sọ pe ọkunrin yi ati awọn Faranse ati Israẹli ti rmulẹ papọ, ati pe on pẹlu Faranse lo ki Israẹli laiya lati gbogun si Egypt.

## Eto Titun Arin Ilu Eko Se

## Ikilo

## Owo Iranlowo

Awọn Onile tabi awọn Onisọbu l'agbegbe apa ibiti Ijọba ti gba, ti nwọn kolti fi iwe tiwọn ranṣẹ si Igbimọ L.E.D.B. fun owo iranlọwọ tiwọn, ki nwọn mọ pe ọjọ 15th Oṣu Dec, 1956 ni asiko ti a nilati da iru iwe bẹ duro.

2. A ko ni da ẹnikẹni ti o ba mu iwe wa lẹhin ọjọ 15th oṣu Dec 1956, lohun.

3. Awọn ẹgbẹ ti o nfi aṣẹ si ki a to fun ni lowo iranlọwọ, iru ẹniti nwọn o gba iwe rẹ ni:-

(a) Awọn ti o gbọjule owo ile ayalegbe nikan fi jẹun, on ati awọn ọmọ rẹ. (b) Tabi awọn onisowo ti a ti wo ṣọbu wọn lulẹ.

4. A le ri iwe ti a fi ngba owo iranlọwọ ni Office L.E.D.B. ni Reclamation Road, Lagos, larin agogo mẹjọ owurọ si agogo kan abọ ọsan.

**C. S. Clover**

**Alaga igbimo owo iranlowo**

## Esu Tun De O

KADUNA—Irohin ti a ri gbo leti Oke-Oya ni wipe a ne kokoro Esu ti yoju ... ilu Bauchi leti ilu Jos, awon si ti de ilu Kano ati agbegbe re, bakanna ni awon ti de Katsina ati Sokoto.

Erufu oşe lo nfę nisisiyi, tabi-tabi ko si wipe boya awon Esu na le de ilę Yoruba nihin; nitorina ogun agbotele ko npa Aro o.

Asiko ti agbado npo nmo niyi, ti awon nkan oko ma nso eso rere bi Jero, Oka baba ati awon nkan bawonni. Ki Olodumare mase fi iyan ba wa ja o.

## Nibo Ni Awon Oku Wa ?

Igbagbo wa ni pe bi enia ba ku, o di gbere nun; a ko tun ni ba eluwa re pade mo, nitori a ko tilo si orun tun pada.

Sugbon ọrọlopo awon enia a ma rohin wipe won ri lagbaja awon ti tamodu. Emi ko gbagbo wipe eyi je otito.

Idi re ti nko fi gbagbo niyi, lagbaja to fi owo ara re ko Petesi meta to fi omo ati aya sile kilo fa a ti o je wipe rise lo tun ri ile re ss?

Nje mo bere lowo enyin okawe wa eniti o ba gbagbo re otito ri nwon eri oku, ki o se alaye fun wa inu re ti o ri ri ati nibo ni awon oku na wa ?

## Rosia ati Egypt ko ni imo po.

MISRA Awon ara ilę Egypt kowe si awon ęgbę Majeobaje wipe, on fę ki nwon se iwadi oro ija to sele larin Egypt, Gesi ati Faranse, ki awon le mo ... paro larin awon ... awon Israeli ... Egypt ati Rosia ... papo, iro ni owon pe.

Egypt ... se pe, ki awon egbe Majeobaje se iwadi nipa iru iwa ika ti Gesi ati Faranse se si ... Port-said, ati awon ... ti nwon lo fun ogun bi Gesi ti se won.

Nitoripe gbogbo bi awon Gesi ti nhuwa ika nwonyi beni a nya aworan re. Enikeni si mo wipe aworan ko npa'ro, chun ti o ba ri ni o nya.

Gbogbo lse buruku ti awon Gesi se ni nwon ti ya aworan re, nwon si ti fi ranse si ile ise awon egbe Majeobaje ki nwon le ri iru iwa ika ti Gesi hu ni Egypt.

## Goldsimiths' Licences, 1957

All Goldsimiths living in Lagos Township who ... to renew their licences for 1957 should apply on Form obtainable at the office of the Chief Administrative Officer (old Colony Office), Broad Street, Lagos not later ... the 15th day of December, 1956.

**(Sgd.) T. I. Kotun.**
**for Chief Administrave Offic...**

Lagos,
21st November, 1956.


# MERCEDES-BENZ

*YOUR GUIDING STAR*
*WHEREVER YOU ARE*

FOR ALL YOUR TRANSPORT NEEDS

- PASSENGER CARS & LORRIES
- TIPPERS, TRACTORS & TRAILERS
- BUSES & SPECIAL PURPOSE VEHICLES
- UNIMOG TRACTORS
- FIRST CLASS "AFTER SALES" SERVICE AT MODERATE CHARGES.

**LEVENTIS MOTORS**

*DISTRIBUTORS FOR NIGERIA*


Printed & Published ... Paper Printing and Publishing Company, ... Street ... P.O. Box 467 Lagos